# IBI MIMỌ́: APẸẸRẸ ISỌDIMIMỌ́

**Ẹksodu 30:1-10; 40:22-28; 29:10-21; Lefitiku 4:1-12; 6:30; Heberu 13:11, 12**

**ẸKỌ 73 FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI:"Sọ wọn di mimọ́ ninu otitọ: otitọ li ọ̀rọ rẹ" (Johannu 17:17).**

### Ibi Mimọ́

A ti kọ́ ninu ẹkọ wa pe bi a ba dá Agọ si ọna mẹta, ipa meji ni Ibi Mimọ́ kó ninu rẹ̀. Awọn alufaa nikan ni o le wọ inu Ibi Mimọ́ yii. Ẹ jẹ ki a wo bi o ti jẹ mimọ́ to.

Wura daradara ni a fi ṣe awọn ogiri rẹ̀ (wura jẹ apẹẹrẹ mimọ), iwa mimọ si jẹ wiwa ni ipo mimọ. Ohun ti a fi bo inu Agọ naa ni ọ̀gbọ̀ wiwẹ, ti a fi ọgbọn hun awọn kerubu si lara. Bi a ba wọ ibi mimọ́ yii, a o ri tabili akara ifihan ni ọwọ ọtun, eyi ti a fi wura daradara bò, lori rẹ si ni akara alaiwú mejila wa, eyi ti o jẹ apẹẹrẹ Ounjẹ Iye, ati Ounjẹ Ẹmi ti awọn ti a ti sọdimimọ n jẹ. Iye akara yii duro gẹgẹ bi ounjẹ fun ẹya Israẹli kọọkan. Ọsọọsẹ ni a maa n paarọ akara yii ki akara titun ba le maa wa nibẹ nigba gbogbo. Njẹ o ranti ọrọ Jesu pe "Emi li onjẹ ìye: ẹnikẹni ti o ba tọ̀ mi wá, ebi kì yio pa a; ẹniti o ba si gbà mi gbọ́, ọrùngbẹ kì yio gbẹ ẹ mọ́ lai" (Johannu 6:35)? Njẹ o ha ri bi Jesu ti fi aworan ara Rẹ̀ ati eto igbala hàn ninu Agọ ti a gbé kalẹ yii ati gbogbo ohun ti a fi ṣe e lọṣọ ati ọna ti wọn n gba sìn nibẹ?

### Imọlẹ

Kò si imọlẹ ninu Agọ yii bi ko ṣe eyi ti o wá lati ori ọpa fitila wura ti atupa meje wà lori rẹ̀, eyi ti a fi wura daradara ṣe. Apá osi ni ọpa fitila yii wà ninu Ibi Mimọ́. Jesu wi pe, "Emi ni imọlẹ aiye; ẹniti o ba tọ̀ mi lẹhin ki yio rin ninu òkunkun, ṣugbọn yio ni imọlẹ ìye" (Johannu 8:12). Nihin ni a ri i pe ọpa fitila yii jẹ aworan Jesu.

Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pẹlu pe, awọn ni imọlẹ aye. Awọn Onigbagbọ ti wọn ya ara wọn sọtọ patapata ni Ijọ ti o n tan imọlẹ si aye. "Lati Sioni wá; pipé ẹwà, Ọlọrun ti tan imọlẹ" (Orin Dafidi 50:2). Sioni ni Ijọ Akọbi, Ijọ ti o jẹ pipé, ti a ti sọdimimọ, ti o si n tàn laaarin okunkun ẹ̀ṣẹ. Awọn ti a ti sọdimimọ ni o n gbadun imọlẹ ọpa fitila wura ti o wà ni Ibi Mimọ́.

### Pẹpẹ Wura

Ni ọ̀kánkán ẹnu-ọna Ibi Mimọ́ ni pẹpẹ turari, ti a n pe ni pẹpẹ wura wà. Wura ni a fi bo oke ati gbogbo ẹgbẹ rẹ̀: ni igun kọọkan ni iwo kan wà, eyi ti awọn alufaa maa n fi diẹ tọ́ ninu ẹjẹ ti wọn mu wá lati inu ẹbọ ẹ̀ṣẹ fun isọdimimọ. Awọn ọpa ti a fi wura bò, ni a fi sinu awọn oruka wura ti o wa ni ẹgbẹ kin-in-ni ati keji, lati fi gbé pẹpẹ yii nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ba n rìn lọ. Pẹpẹ wura ni o wà lẹgbẹ aṣọ ikele ti o wà laaarin Ibi Mimọ́ ati Ibi Mimọ́ Julọ. Nịgbakuugba ni a maa n sun turari nibẹ, gẹgẹ bi apẹẹrẹ adura ati iyin igbà gbogbo si Ọlọrun.

### A Ya Agọ Naa si Mimọ́

Nigba ti iṣẹ́ kikọ́ Agọ yii pari, Oluwa fun Mose ni aṣẹ lati pese ororo ti a o fi ya Agọ́, Apoti-majẹmu, tabili wura ati awọn awo rẹ, ọpa fitila ati ohun elo rẹ, pẹpẹ wura, pẹpẹ idẹ ati agbada omi, sọtọ -- a gbọdọ ya gbogbo wọn si mimọ́ fun lilò ninu isin Ọlọrun. Aarọni ati awọn ọmọ rẹ, awọn alufaa, ni a gbọdọ fi ororo yà si mimọ́ pẹlu. Ororo jẹ apẹẹrẹ Ẹmi Mimọ eyi ti o n farahàn nigba ti a ba ri igbala ati isọdimimọ́, ṣugbọn a ki i gbadun ibagbe rẹ̀ titi bi ko ṣe igba ti a ba ni ifiwọni Ẹmi Mimọ́.

### Isọdimimọ Nipa Ẹjẹ

O gbà ju ororo lati ya awọn alufaa ati Agọ́ si mimọ́. "Bẹ gẹgẹ li o si fi ẹ̀jẹ wọ́n agọ́, ati gbogbo ohun èlo isin" (Heberu 9:21), lẹyin ti a ba si ti fi omi wẹ awọn alufaa ti a si fi ororo yàn wọn, a o pa àgbò kan, a o si fi ninu ẹjẹ rẹ si eti ọtun wọn, atampako ọwọ ọtun wọn ati atampako ẹsẹ ọtun wọn, eyi ti i ṣe apẹẹrẹ pe ẹjẹ naa ti bò wọn patapata lati sọ wọn di mimọ́. Wọn kò le wọ Ibi Mimọ́ ninu Agọ́ titi a o fi ṣe iwẹnumọ́ yii.

Rò bi Agọ yii ti jẹ mimọ́ to. Ẹ jẹ ki a kọ ronu nipa bi awọn ohun elo ti a fi ṣe ile yii ati ọṣọ́ rẹ ti jẹ pipe to – wura daradara ati ọ̀gbọ̀ wiwẹ́. Lẹyin naa ni a fi ororo ati ẹjẹ yà á si mimọ́, a si yà awọn alufaa si mimọ́ ki wọn to le wọle. Njẹ iwọ ko ha ri bi iwa mimọ́ ti ṣe pataki to loju Ọlọrun? O sọ fun awọn eniyan pe: "Nitorina ni ki ẹnyin ki o yà ara nyin simimọ́, ki ẹnyin ki o si jẹ́ mimọ́; nitoripe mimọ́ li Emi" (Lefitiku 11:44).

A ko le sọ pupọ nipa aṣọ awọn alufaa, ṣugbọn a fẹ mẹnu kan fila, tabi adé, ti olori alufaa n dé. Lara rẹ̀ ni awo pẹrẹṣẹ wura daradara kan wà, lara eyi ti a kọ awọn ọrọ wọnyii si, MIMỌ́ SI OLUWA. Nigbakuugba ti awọn eniyan ba wo Aarọni, wọn yoo ranti bi Ọlọrun ti jẹ mimọ́, wọn yoo si mọ aini wọn nipa iwa mimọ́ pẹlu, ki wọn ba le jẹ ẹni itẹwọgbà lọdọ Oluwa.

### Ẹbọ Ẹṣẹ

A kà ninu Lefitiku ori kẹrin nipa ẹbọ ẹṣẹ ti a n fi akọ maluu tabi ọmọ ewurẹ ṣe fun awọn ẹṣẹ kan. Eyi ki i ṣe ọ̀kan naa pẹlu ẹbọ irekọja, nigba ti ẹni kọọkan mu ọdọ-agutan ti rẹ̀ wá lati fi ṣe ẹbọ fun ẹṣẹ (irekọja) rẹ̀. Lẹyin ti a

ba ri igbala, ti a gba idariji ẹṣẹ ti a ti dá, o yẹ ki a ni isọdimimọ nipa eyi ti a o wẹ ẹṣẹ abinibi, ti i ṣe ẹda ẹṣẹ ti a ti jogun lati ọdọ Adamu, nù.

Bi wọn ba ti pa akọ maluu tabi ọmọ ewurẹ yii, alufaa yoo mu diẹ ninu ẹjẹ rẹ, yoo wọ inu Ibi Mimọ́ lọ, yoo si wọ́n ọn nigba meje "niwaju OLUWA, niwaju aṣọ-ikele." Ranti pe Apoti-Majẹmu ati Itẹ-Aanu wà lẹyin pẹpẹ wura, ni odi keji aṣọ-ikele, ifarahan Ọlọrun si wà laaarin awọn kerubu ti wọn wà lori Itẹ-aanu. Bi wọn ti n wọ́n ẹjẹ naa sori pẹpẹ wura, aṣọ-ikele nikan ni o wà laaarin rẹ ati Ṣẹkina. A o fi diẹ ninu ẹjẹ naa sori iwo mẹrin ti o wa ni igun pẹpẹ wura pẹlu.

**A Sun Ún Lẹyin Ibudo**

Diẹ ninu ẹbọ ẹṣẹ ni a n sun lori pẹpẹ idẹ. A oo mu iyoku lọ sẹyin ibudo nibi ti a o ti sun un patapata. Ẹkọ wo ni a ri kọ́ ninu eyi?

Ẹbọ ẹṣẹ yii ni ohun ti Paulu sọ nipa rẹ ninu Heberu 13:11, 12. Ẹran ti a pa, ti a mu ẹjẹ rẹ lọ si Ibi Mimọ́, ti a si wọ́n ọn sori pẹpẹ turari, ni a sun lẹyin ibudo gẹgẹ bi aworan ijiya Jesu lori oke Gọlgọta, lẹyin ilu Jerusalẹmu, ti O si ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati fi sọ awọn eniyan Rẹ̀ di mimọ́. Paulu sọ dajudaju pe: "ki o le fi **ẹ̀jẹ** ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́."

**Ẹjẹ ṣe Pataki**

A fẹ tẹnu mọ́ ọn pe ẹjẹ ni o le sọ awọn eniyan di mimọ́. Awọn miiran fẹ ki a gbagbọ pe ororó (ti o le fi we Ẹmi Mimọ́) ni o n sọ ni di mimọ́, (lootọ ni Ẹmi Ọlọrun maa n farahàn nigbakigba ti a ba ni iriri Onigbagbọ, nitori Kristi mí Ẹmi Mimọ si awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni ọjọ kin-in-ni ti O jinde kuro ninu okú (Johannu 20:22), ṣugbọn wọn kò gba ifiwọni agbara Ẹmi Mimọ́ titi di ọjọ Pẹntekọsti). A fi ororo yan Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀, ṣugbọn a ni lati fi ẹjẹ si eti, atampako ọwọ, ati atampako ẹsẹ wọn ki wọn to le di mimọ́ lati wọ inu Ibi Mimọ́.

Awọn miiran fẹ ki a gbagbọ pe agbada omi ti o wà ni agbala ode nibi ti awọn alufaa ti n wẹ̀ jẹ́ apẹẹrẹ isọdimimọ, ṣugbọn kò si ẹjẹ ninu agbada omi yii – Jesu ni O n fi Ẹjẹ Rẹ̀ sọ wa di mimọ́! A mọ pe agbada omi yii jẹ apẹẹrẹ iribọmi.

Awọn miiran wi pe ẹbọ ohun-jijẹ naa (ninu eyi ti akara alaiwu, iyẹfun kikuná, ororo ati turari wà) jẹ apẹẹrẹ isọdimimọ; ṣugbọn a ri pe ko si ẹjẹ ninu eyi pẹlu. A le ri ifararubọ wa ninu awọn ẹbọ wọnyii. A gbọdọ mu ohun ti o dara julọ wa, lai si ẹṣẹ (iwukara), turari adura wa ti o n goke nigba gbogbo lati inu ọkàn wa yoo gbé ifararubọ wa lọ sọdọ Oluwa. Ẹmi (òróró) yoo fi ibukun sori ẹbọ wa, ṣugbọn a gbọdọ duro ki Jesu fi Ẹjẹ Rẹ̀ wẹ ọkàn wa ni igba keji ki a to le sọ wa di mimọ́. (Igba kin-in-ni ti Ẹjẹ Jesu wẹ ọkàn wa ni igba ti a ri igbala, nigba ti a mu ẹbọ wa ti i ṣe ọdọ-agutan wa gẹgẹ bi ẹbọ irekọja).

Awọn alufaa nikan ni o le wọ inu Ibi Mimọ́. Olori alufaa yoo wọ igbàya ti a to okuta si lara ti a fin orukọ awọn ẹya Israẹli mejila si. Bayii ni a ṣe n ṣe aṣoju awọn eniyan wọnyii niwaju Ọlọrun nidi pẹpẹ wura ti isọdimimọ. Ki i ṣe ẹjẹ akọ maluu ti o wà lori pẹpẹ wura ni o n sọ awọn eniyan naa di mimọ́, ṣugbọn o jẹ apẹẹrẹ Ẹjẹ Jesu ti yoo wá; ati nipa wiwò Ó pẹlu igbagbọ, gbogbo wọn ni a le sọdimimọ́ ni ọjọ wọnni naa pẹlu, nitori, a sọ awọn miiran di mimọ́.

**Iwa Mimọ́ ṣe Pataki**

Njẹ iwa mimọ́ ṣe danindanin fun wa? Bi Ọlọrun ba sọ fun awọn Ọmọ Israẹli pe "Nitorina ki ẹnyin ki o si jẹ mimọ́, nitoripe mimọ́ li Emi", bawo ni o ti jẹ ọranyan fun wa to ni igba aye "oore-ọfẹ" yii, lẹyin ti Jesu ti ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun isọdimimọ wa! Bi Ọlọrun ba paṣẹ gidigidi pe gbogbo nnkan ti o wà ninu Agọ ti ayé yii gbọdọ jé mimọ́, ati pe awọn eniyan mimọ́ nikan ni o le wọ inu rẹ, njẹ iwọ rò pé ẹnikẹni le wọ Agọ nlá ti Ọrun lai si iwa mimọ́? "Ẹ mã lepa alafia pẹlu enia gbogbo, ati ìwa mimọ́, li aisi eyini kò si ẹniti yio ri Oluwa" (Heberu 12:14).

Bawo ni a ṣe le di mimọ́? A ti gbà wá là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa nipasẹ ironupiwada, a si ti bẹ Jesu lati fi Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye bo o mọlẹ. O ti dari gbogbo aiṣedeedee wa ji wa, O si ti fun wa ni agbara maa lọ, má dẹṣẹ mọ́. Ṣugbọn a wa ni agbala ode sibẹ. Bawo ni a ṣe le wọ Ibi Mimọ́ bi o ba jẹ awọn alufaa nikan ni o le wọ ibẹ?

**Ọba ati Alufaa**

Peteru wi nipa awọn Onigbagbọ pe: "Ṣugbọn ẹnyin ni iran ti a yàn, olu-alufa, orilẹ-ède mimọ́, enia ọ̀tọ; ki ẹnyin ki o le fi ọla nla ẹniti o pè nyin jade kuro ninu òkunkun sinu imọlẹ iyanu rẹ̀ hàn" (1 Peteru 2:9). Johannu sọ nipa rẹ pẹlu pe: "Ẹniti o fẹ wa, ti o si wẹ̀ wa ninu ẹ̀jẹ rẹ̀ kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa, ti o si ti fi wa jẹ ọba ati **alufa** fun Ọlọrun ati Baba rẹ̀" (Ifihan 1:5, 6).

Nitori naa bi awa ba jẹ alufaa Ọlọrun, awa pẹlu le mú ẹ̀jẹ ẹbọ ẹ̀ṣẹ lọ sinu Ibi Mimọ́ fun isọdimimọ wa, ki a si gbadun inu ile wura ti o n dán, ti a si ti wẹ̀ mọ́ yii.

Iwa mimọ́ ti ni ẹwa to! A ti wọ inu Ibi Mimọ́ Ọlọrun, a si ti ni idapọ pẹlu Jesu, Olori Alufaa wa. "Nitori ati ẹniti nsọ-ni di mimọ́ ati awọn ti a nsọ di mimọ́, lati ọdọ ẹnikanṣoṣo ni gbogbo wọn: nitori eyiti kò ṣe tiju lati pè wọn ni arakunrin" (Heberu 2:11). A jẹ ninu akara ifihan ti Ọrun a si gbadun imọlẹ ologo ti o n tàn lati ori ọpa fitila wura.

## AWỌN IBEERE

1. Ṣe apejuwe Ibi Mimọ́. Awọn wo ni o le wọ inu rẹ̀?
2. Ki ni a fi n rubọ lori pẹpẹ wura?
3. Apẹẹrẹ ki ni ọpa fitila jẹ́?
4. Ki ni tabili akara ifihan duro fun?
5. Ki ni ṣe ti Jesu jiya lẹyin ibudo?
6. Njẹ iwa mimọ́ ṣe dandan fun wa lonii?